
*YORUBA – "The Two Roads"*

# Awọn Ọ̀nà Mejeji



## Yíyan ọ̀nà

Nigbakugba tí a bá pinu láti rin ìrìn àjò paapa lọ si ibi tí a ò dé rí, a ó rò lemi wa pé ọ̀nà wo ni a ó gbà dé ibi tí a ń lọ yi. Ninu irin-ààjò yìí, a ó la ojú wa sílẹ̀ ati pe ni kété ti a ba ri pe a ò sí lọ́nà írin-ààjò naa ni a o padà láti wa ọ̀nà ti o tọ si ibi ti à ń lọ.

Bẹ́ẹ̀ náà lórí fun ìrẹ ati èmi paapa. Ojojúmọ́ l'a n rín ìrìn ájò lọ si ilẹ̀ kan tí a kò mọ, ibi ti ko si rọrùn lati pada loju ọ̀nà wíwọ́ ti a rin dé bẹ̀. Ǹjẹ́ o mọ ibi tí ò ńlọ náà?

## Ìwé ìtọ́ni náà

Ọlọrun ninu àánú rẹ ti fi ìwé itọni fun wa, eyi ni Bíbélì mímọ́ eyi ti o n fi ọ̀nà ọ̀run rere hàn wá.

Gbogbo àyọlò ti a lo ninu àtẹ̀jáde yii wá lati inu ìwé mímọ́ náà ''BIBELI'' Ọrọ̀ Rẹ ni fitílà fún ẹsẹ mi, ati ìmọ́lẹ̀ si ipa ọ̀nà mi. (Orin Dafidi 119:105)

## Ònà gbòòrò

Ogunlógọ̀ àwọn eniyan lo n rin lọ́nà yii . . . "gbooro li ẹnu-ọna naa, ati onibu li ojuọna naa ti o lọ si ibi iparun; ọ̀pọ̀lọpọ̀ li awọn ẹni ti ń bá ibẹ̀ wọlé" (Matt 7:13).

Púpọ̀ nínú àwọn ènìyàn naa lo di ojú wọn pinpin. Wọn o mọ, bẹẹ ni wọn o si fẹ mọ pe awọn wa lójú ọ̀nà ìparun. "Ọna kan wa tí ó dàbí ẹni pe ó dára lí ojú ènìyàn, ṣùgbọ́n opin rẹ li ọ̀nà ikú" (Owe 14:12). "Ninu awọn ẹni ti Ọlọrun aye yi (Satani) ti sọ ọkan awọn ti ko gbagbọ di afọju" (II Korinti 4:4).

## Erù náá

Awọn eniyan oju ònà yì ti ru àrùwọrùn ẹrù ẹ̀ṣẹ̀ "Gbogbo eniyan li o sa ti ṣẹ, ti wọn si kùnà Ògo Ọlọrun:" (Rom 3:23) Ko ṣeṣe fun wa lati fi ẹ̀ṣẹ̀ pamọ fun Ọlọrun . . . "ènìyàn a maa wo oju, Oluwa a maa wo ọkan" (I Sam 16:7) A ti de ẹrù naa mọ wọn lẹ́hìn. Ko ṣeṣe fun iwọ ati emi lati bọ kúrò lọ́wọ́ ẹ̀ṣẹ̀ pẹlu agbára wa bẹẹ si ni ẹrù naa n wuwo sii. "Ikú ni èrè ẹ̀ṣẹ̀" (Rom 6:23).

## Ìmọ́lẹ̀ náà

Imọ́lẹ̀ ti a n wo ninu awọran yii ni ìdájọ́ Ọlọrun. "Níwọ̀n bi a si ti fi lélẹ̀ fun gbogbo eniyan lati ku lẹẹkanṣoṣo, ṣugbọn lẹhin eyi ìdájọ́": (Heb 9:27) "Mo si ri itẹ funfun n la kan, ati ẹni ti o joko lórí rẹ . . . Mo si ri awọn oku, àti èwe àti àgbà, wọn duro níwájú itẹ; . . . a si si awọn ìwé miran kan sílẹ̀ ti iṣe ìwé ìyè . . . a si dájọ́ fún àwọn oku lati inu ohun tí a ti kọ sínú àwọn ìwé náà, gẹ́gẹ́ bí iṣẹ wọn . . . Bi a ba si ri ẹnikẹ́ni ti a ko kọ orúkọ rẹ sínú ìwé ìyè, a sọ ọ sínú adágún iná (Ifihan 20:11, 12, 15).

## Adágún iná

Nitori pe Ọlọrun jẹ́ mímọ́ ati Olootọ o di dandan kí ìjìyà wa fun ẹ̀ṣẹ̀. Ọlọrun ti jẹ́ kí o di mímọ̀ fun wa pe ibùgbé kan wa ti a ti pẹṣẹ sílẹ̀ fun àwọn ẹlẹ́ṣẹ̀ eyi ni adágún ina (ọ̀run àpáàdì) Bibeli sọ fun wa pe "Ori awọn eniyan buburu li a o da si ọ̀run àpáàdì, ati gbogbo orilẹ -ede tí ó gbàgbé Ọlọrun" (Orin Dafidi 9:17) Kò í ṣe igbàtí a ba pe ọ l'eniyan búburú lo to le nípín nínú iná yii, bi ẹnikẹ́ni ba gbàgbé Ọlọrun irú ẹni bẹẹ yoo jẹ alábàpún nínú iná pẹ̀lú.

Síbẹ̀ síbẹ̀, Ọlọrun jẹ aláàánú ". . . kò fẹ́ kí ẹnikẹ́ní kí ó ṣègbé, bíkòṣe kí gbogbo ènìyàn kí ó wá sí ìrònúpìwàdà" (II Pet 3:9).

Nínú ọ̀pọ̀ àànú Ọlọrun, O ti sèètò ọ̀nà ati yọ fun ẹnìkẹni tí ó bá fẹ yọ kúrò ninu ikú ẹ̀ẹ̀kejì yìí. N jé, ìwọ gan an ń fẹ ọ̀nà ìyè yi?

## Ọ̀nà ìyè

Nítorí pé ènìyàn kò le dá ara re já gbà kúrò lọ́wọ́ ẹ̀ṣẹ̀ tàbí kúrò nínú ìjì ẹ́ṣẹ̀. Ọlọrun ti pèsè olùgbàlà. "Nitorí Ọlọrun fẹ́ aráyé tobẹ gẹ ẹ ti O fi Ọmọ bíbí rẹ kanṣoṣo fun ni, ki ẹnikẹ́ni tí ó bá gba a gbọ ma ba ṣègbé, ṣùgbọ́n kí o le ni ìyè ainipẹkun" (Johanu 3:16) Ọlọrun, baba wa ọ̀run ran ọmọ Rẹ kan ṣoṣo, eyi ni Jesu Kristi wá sínu ayé yìí lati ọrun; ó gbé gẹ́gẹ́ bí àwa ènìyàn ṣùgbọ́n láì dẹ́ṣẹ̀. O lọ kaakiri lati ṣe rere, o wo awọn aláìlera sàn, ó mú kí adẹ́tẹ̀ san ninu ẹ̀tẹ̀ wọn, o ba ẹmi aimọ wi, o dari jin awọn ẹlẹ́ṣẹ̀ ti o ronupiwada o si tun kọ awọn eniyan ni ọ̀nà ti Ọlọrun.

Parípari rẹ, ó wá láti kú gẹ́gẹ́ bí ètùtù fun ẹ̀ṣẹ̀ ti Oun ko da. Lati ta ẹjẹ Rẹ iyebíye silẹ fun ìmúkúrò ẹṣẹ gbogbo ènìyàn. O gba awọn eniyan buburu laaye lati fi ìyà jẹ Oun, láti kan òun mọ́ igi àgbélèbú ninu oró ńlá. ''Eni ti oun tikararẹ fi ara rẹ ru ẹ̀ṣẹ̀ wa lórí igi,'' (I Pet 2:24) Ó kú fún ọ àti fún èmi pẹ̀lú.

## Ajinde rẹ

Lẹhin ọjọ mẹta ni isà òkú, Jesu jí dìde kúrò nínú òkú. Ó rìn pẹ̀lú awọn ọmọ -ẹ̀hìn, ó sì bá wọn sọ̀rọ̀ kí o to wa gòkè lọ s'ọ́run lẹ́hìn ogóji ọjọ lori ilẹ̀ lẹhin àjíride Rẹ lati lọ joko l'ọwọ Ọ̀tún Ọlọrun alàáyè; Olugbala to wa laaye pẹlu ''. . . gbogbo agbara li ọrun ati li aye'' . . . (Matt 28:18) Nitori naa, o si le gba wọn la pẹ̀lú títí dé òpin, ẹnití o ba tọ Ọlọrun wa nípaṣẹ̀ rẹ nitori ti o m bẹ laaye titi lae lati maa bẹ̀bẹ̀ fún wọn (Heb 7:25).

## Ọ̀run rere

Ọrun yi ni ibùgbé ọlọrun pẹlu Ọgo Rẹ. Oluwa wa Jesu Kristi sọ pe ''Nitori emi n lọ peṣe àáyè sílẹ̀ fun yin, Bi mo ba si lọ ipeṣe aaye silẹ fun yin, emi o tun pada wa, emi o si mu yin lọ sọdọ emi tikarami; pe nibi ti emi gbe wa, ki eyin le wa nibe, pẹlu'': (Joh 14:2-3).

Ibiti ko láfiwé lati ni à fi jọ nibi ti Ọlọrun yoo si nu omyé gbogbo nu kuro li oju wọn; ki yoo si ikú mọ́ tabi ọ̀fọ̀, tabi ẹkún, bẹẹ ni ki yoo si irora mọ, nitori pe ohun atijọ ti kọja lọ'' . . . Ati pe oru ki yoo si si mọ nitori pe Oluwa Ọlọrun ni yoo tan ìmọ́lẹ̀ fun wọn (Ifihan 21:4, 22:5). Ibi mímọ́ ni ibi tí a n wi yi, ''Ohun aláìmó kan ki yoo si wọ inú rẹ rara, tabi ohun ti n siṣẹ ìríra ati èké; bikoṣe awọn ti akọ sinu iwe ìyè ọdọ Agutan (Ifihan 21:27).

Ọna horo kan lo n tọka si ọrun yi ''Jesu wi fun ni pe, Emi ni ọna ati otitọ, ati iye: Ko si ẹnikẹni ti o le wa sọdọ Baba, bikoṣe nipaṣẹ mi.'' (Joh 14:67) Bẹẹ si ni ''Ko si igbala lọdọ elomiran: nitori ko si orukọ miran labẹ ọrun nipa eyi ti a le fi gba wa la (Iṣe A A 4:12).

## Báwo la ṣe le de oju ọ̀nà yìí?

1. Ronupiwada, ki o si gba ìhinrere gbọ. (Mark 1:15) Lati ronupiwada ni láti kọ ẹ̀ṣẹ̀ Sílẹ̀, ki osi yi pada si Oluwa Ọlọrun rẹ lọ́tun.
2. Wa sọdọ Jesu Kristi ninu adura pẹlu ẹrù ẹ̀ṣẹ̀ rẹ: Bẹbẹ fun ìdáríjìn nitori pe Jesu wipe ''eniti o ba tọ mi wa, emi ki yoo ta a nu'' (John 6:37) Bakannaa, lo tun wipe ''E wa sọdọ mi gbogbo ẹyin ti n siṣẹ, ti a si di ẹru wuwo le lori, emi o si fi isinmi fun yin (Matt 11:28).
3. Gba Olugbala gbọ fun igbala rẹ . . . ''ẹ̀jẹ̀ Jesu Ọmọ rẹ ni n wẹ wa nù kúrò nínú èṣè gbogbo'' (I Joh 1:7).
4. Yoo fun ọ ni ìgbé ayé tuntun àti ìyè ainipekun – Jesu sọ pe ẹnikẹni ti o ba gbọ ọ̀rọ̀ mi, ti o ba si gba ẹniti ó rán mi gbọ́, o ni ìyè ti ko nipẹkun, oun ki yoo si wa si ìdájọ́, ṣugbọn o ti re ikú kọjá bọ si ìyè. (Joh 5:24) Nitori naa, bi ẹnikẹni ba wa ninu Kristi, o di ẹda titun ohun atijọ ti kọja lọ, kíyèsi wọn si di titun. (II Kor 5:17).
5. Wà á ní àlàáfíà ati ìdánilójú ìgbàlà rẹ – ''N jẹ̀ bi a sì ti ń da wa láre nípa ìgbàgbọ́ àwa ni alaafia lọ́dọ̀ Ọlọrun nípa oluwa wa Jesu Kristi'' (Rom 5:1).

‘‘Eri naa si li èyí pe Ọlọrun fun wa ni ìyè ainipẹkun, ìyè yi si n bẹ nínú Ọmọ Rẹ. Eni tí ó ba ni Ọmọ ó ní ìyè; ẹni tí ko ba si ni Ọmọ Ọlọrun, kò ní ìyè. N kan wọnyii ni mo kọwé rẹ si yin àní sí ẹyin ti ó gba orukọ ọmọ Ọlọrun gbọ́, ki ẹyin ki o le mọ pe ẹ̀yín ní ìyè ainipẹkun, àní fun ẹ̀yin ti o gba orúkọ ọmọ Ọlọrun gbọ́ (I Joh 5:11-13).

## Bí o ti ṣé le gbé ìgbé ayé titun náà

1. Ka Bibeli rẹ lojojumọ – Yatọ si pe o jẹ̀ imọlẹ si ọ̀nà rẹ, o tun jẹ onjẹ̀ ẹmi ‘‘Bi ọmọ ọwọ́ titun, ki ẹ maa fẹ wàrà ti ẹmi naa eyiti ko li ẹtan, ki ẹyin ki o le ma ti ipaṣẹ̀ rẹ dagba si ìgbàlà.’’ (I Pet 2:2) Gbadura fun itọni ati ìkọ́ni Emí mímọ́ Ọlọrun nigbakugba ti o ba fẹ ka a.

2. Sun mọ Ọlọrun nipa gbigbadura lojojumọ – Gbadura l’orukọ Jesu ‘‘E maṣe àníyàn ohun kohun, ṣugbọn ninu ohun gbogbo, nipa adura ati ẹ̀bẹ̀ pẹ̀lú ìdúpẹ́, ẹ maa fi ìbéèrè yin han fun Ọlọrun. Ati alaafia Ọlọrun ti o ju ìmọ̀ràn gbogbo lọ, yoo sọ ọkan ati ero yin ninu Kristi Jesu.’’ (Filippi 4:6, 7).

3. Ba awọn eniyan sọrọ nipa Jesu – ‘‘Lọ, si ile rẹ ki o si sọ fun ará ilé rẹ bi Oluwa ti ṣe ohun n la fun ọ ati bi o si ti saanu fun ọ (Mark 5:19).

4. Pe olúwa nínú ìdánwò – ‘‘Nitori niwọn bi Oun tikararẹ ti jìyà nipa ìdánwò, o le ran awọn ti a n danwo lọwọ’’ (Heb 2:18).

5. Ti o ba ṣèèsì bọ sinu ẹ̀ṣẹ̀, jẹ́wọ́ re lẹ́sẹ̀kẹṣẹ̀ fun Ọlọrun – ‘‘Bi awa ba jẹ́wọ́ ẹ̀ṣẹ̀ wa, olootọ ati Olododo ni Oun lati dari ẹṣẹ wa jìn wá ati lati wẹ̀ wá nù kúrò ninu aiṣododo gbogbo. (I John 1:9).

6. Gbìyànjú lati maa darapọ̀ mọ́ àwọn eniyan ti o ni igbagbọ nínú Kristi Jesu – ‘‘Eyi ni ofin mi, pe ki ẹyin o fẹran ara yin, gẹgẹ bi mo ti fẹran yin (John 15:12).

7. Ri pe o n gba ohun Ọlọrun gbọ nigbagbogbo – ‘‘Bí ẹnikẹni ba fẹran mi, yoo pa ọ̀rọ̀ mi mọ. (John 14:23).

8. Ma sẹ bẹ̀rù ohunkohun nítorí Olùgbàlà wa pẹ̀lu rẹ – ‘‘Emi ko jẹ fi ọ sílẹ̀ bẹẹ ni emi ko jẹ kọ ọ silẹ (Heb 13:5).

9. Sẹ́ pá ṣẹ́ ṣẹ̀ fun Jesu (fi gbogbo aye rẹ fun lai ku) Jẹ́ kí o dari ayé rẹ bi o ti tẹ E lọ́rùn. Ninu eyi lo ni ìdùnnú ati ayọ̀ tí ó pé.

Ti o ba ri idande nínú Jesu tabi a ti ibukun o nipa kika atẹ kọ wọnyii, jọwo jẹ ki á mọ̀.

A fẹ yin Ọlọrun logo pẹlu rẹ, a o si fẹ maa ranti rẹ ninu adura wa fun imuduro dopin.

---

If you have found salvation in Christ, or have been otherwise blessed through our Gospel literature, please let us know. We would like to thank God with you, and remember you further in our prayers. **Our Heart of Man Book can now be downloaded in 480 different languages onto cell phones, tablets, etc from our website www.angp-hb.co.za.**

For **free** Gospel literature, books and tracts in over 540 languages, write to:
**E-MAIL: info@angp.co.za**
**ALL NATIONS GOSPEL PUBLISHERS**
**P.O. Box 2191, PRETORIA, 0001, R.S.A.**
(A Gospel Literature Mission financed by donations)
(Reg. No. 1961/001798/08)